السنّة النبوية وعلومها
www.sunnah.global

# Kii ṣe ẹniti n fi dáadáa ṣẹ̀san dáadáa ni ó pé perepere nibi siso okùn-ẹbi, ṣugbọn oluso okùn-ẹbi gangan ni ẹniti ó jẹ́ pé nigba ti awọn eniyan bá já okùn-ẹbi rẹ̀ dànù, ó maa n so o padà

Lati ọdọ Abdullah ọmọ Amr- ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji - o gba a wa lati ọdọ Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba - ó sọ pé: "Kii ṣe ẹniti n fi dáadáa ṣẹ̀san dáadáa ni ó pé perepere nibi siso okùn-ẹbi, ṣugbọn oluso okùn-ẹbi gangan ni ẹniti ó jẹ́ pé nigba ti awọn eniyan bá já okùn-ẹbi rẹ̀ dànù, ó maa n so o padà".

[O ni alaafia] [Bukhaariy gba a wa]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - n sọ fún wa pé dajudaju eniyan tó pé nibi siso okun-ẹbi ati ṣiṣe daadaa si awọn ibatan rẹ̀ kii ṣe eniyan tí ó ń san daadaa pẹlu daadaa nikan, bi ko ṣe pé ẹniti ó ń so okun-ẹbi gangan, tó sì pé nibi siso okun-ẹbi ni ẹnití o jẹ́ pé bí wọ́n bá já okun-ẹbi rẹ̀, ó maa so o padà, kódà bí wọ́n bá ṣe aburú si i; dáadáa ni oun maa ṣe sí wọn padà.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3854

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY

لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee